UK Health Security Agency

NHS

## Ìtọ́sọ́nà kan si ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára

# ní ọmọ ọdún kan



**Ṅṣe àfihàn àwọn ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára lati Osu Kesan ọdun 2024**

immunisation
the safest way to protect your child

# Ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára èwe

**Rántí** láti mú Ìwépupa abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ wá pẹ̀lú rẹ sí ibi ìpàdé kọ̀ọ̀kan.




Àwọn ẹ̀dà ìwé wọ̀nyí wà láàrọ́wọ́tó láti ilé ìwòsàn tàbí dókítà alábẹ rẹ. Wo **www.nhs.uk/vaccinations pẹlu**

Ìwé pélébé yìí ńṣe àfihàn àwọn ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára lati Osu Kẹsan ọdun 2024

# Lákòótán

## Ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára wo ni ọmọ mi yóò gbà ni ọmọ ọdún kan?

Ọmọ rẹ yóò gba àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára ni àkókò àbẹ̀wò ọdún kan wọn èyítí ó pẹ̀lu:

- àlékún abẹ́rẹ́ àjẹsára **MenB** wọn
- abẹ́rẹ́ àjẹsára **Hib/MenC** tako:
    - Hib (Haemophilus influenzae type b), àti
    - Ààrùn meningococcal ìpín C (MenC)
- àlékún abẹ́rẹ́ àjẹsára **PCV13** tako:
    - Ààrùn pneumococcal tí irú kòkòrò ààrùn fà
- abẹ́rẹ́ àjẹsára**MMR** àkọ́kọ́ wọn tako:
    - ìta
    - Ara wíwú
    - rubella



# Àwọn ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ní ọjọ́-orí ọdún kan

## Dídàábò tako Hib, ààrùn meningocuccal ipin B àti C, ààrùn pneumococcal, ìta ilẹ̀, ara wíwú ati rubella

### Kíni Hib?

Hib jẹ́ àrànmọ́ tó le yọrí sí ọ̀pọ̀ àwọn àìlera gbòógì bíi kọ́ọ́lí (ìtẹ̀nú ọpọlọ wíwú), septicaemia (májèlé ẹ̀jẹ̀) àti òtútù àyà, pàápàá jùlọ nínú àwọn ọmọ wẹrẹ.

Abẹ́rẹ́ àjẹsára Hib/MenC ni à ńpè ní Menitorix, o le wo Ìwé-pélébé Ìwífún Aláìsàn ní www.medicines.org.uk/emc/product/167/pil.

### Kíni ààrùn meningococcal?

Ààrùn Meningococcal jẹ àrànmọ́ líle tí o le fa kọ́ọ́lí ati septicaemia nínú àwọn ọmọde àti awọn ọ̀dọ́.

Ààrun meningococcal ìpín B (MenB) ló ńfa ọpọlọpọ ìsẹ̀lẹ̀ ààrùn meningococcal lọwọlọwọ ni orilẹ-ede UK, bí ààrùn meningococcal ìpin C (MenC) kò ṣe wọ́pọ̀ nisisinyi nitoripe ọpọlọpọ awọn ọmọ wẹrẹ ati awọn agunbanirọ ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tako MenC.

Abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB ni à ńpè ní Bexsero, o le wo Ìwé-pélébé Ìwífún Aláìsàn ní www.medicines.org.uk/emc/product/5168/pil.

## Awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára wo ni yóò jẹ́ lílò?

Ọmọ rẹ yoo gba apapọ abẹrẹ àjẹsára Hib/MenC ati alekun abẹrẹ àjẹsára MenB. Awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára wọnyi yoo jẹ gbigba sinu isan itan tabi oke apa.

## Kilode ti ọmọ mi ṣe nilo awọn alekun abẹ́rẹ́ àjẹsára?

A funni ni awọn alekun abẹ́rẹ́ àjẹsára lati mu ki aabo ti a ti fun ọmọ rẹ gberu nipaṣe awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára to ti gba tẹlẹ. Aabo ti awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára ìkókó npese le yọ́tan lẹyin igba diẹ. Alekun abẹ́rẹ́ àjẹsára kan nmu ki akoko aabo gun si sinu igbe-aye ọjọ iwaju.

## Ǹjẹ́ awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára Hib/MenC ati MenB ni idiju kankan?

Ọmọ rẹ le ni ara pipọn, wiwu tabi rirọ nibi oju abẹrẹ naa. Bi idaji awọn ọmọde to gba abẹ́rẹ́ àjẹsára naa le ni inira, ti awọn kan si ni ibà díẹ̀. O le ni awọn iwifun siwaju sii lori eyi lati ọdọ GP rẹ, osiṣẹ nọọsi rẹ tabi alejo ilera.



## Kíni ààrùn pneumococcal?

Ààrùn pneumococcal jẹ ọkan lara awọn okunfa ààrun kọọli to wọpọ ninu awọn ọmọde sugbọn o tun ma nfa septicaemia, otutu aya, ààrun eti (otitis media) ati awọn ailera miiran to le. Orisirisi iru kokoro aarun pneumococcal ju 90 lọ.

## Abẹ́rẹ́ àjẹsára wo ni yóò jẹ́ lílò?

Abẹ́rẹ́ àjẹsára ti a lo ni alekun abẹrẹ PCV13 (abẹrẹ ajẹsara pneumococcal) ti o npese aabo tako orisirisi iru pneumococcal 13 ti o nsaba fa ààrùn pneumococcal ninu awọn ọmọde.
A o gun abẹrẹ ajẹsara yii sinu isan itan tabi oke apa ni akoko abẹwo kanna gẹgẹbi awọn abẹre ajẹsaraHib/MenC ati MenB.

## Ǹjẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára PCV yóò ní àwọn ìdijú kankan?

Nínú awọn ọmọ mẹwa to ti gba abẹrẹ ajẹsara, ọkan tabi meji ma n ni ara wiwu, pipọn tabi rirọ ni oju abẹrẹ tabi ni iba kekere kan. Abẹ́rẹ́ àjẹsára PCV ni à ńpè ní Prevenar 13, o le wo Ìwé-pélébé Ìwífún Aláìsàn ní www.medicines.org.uk/emc/product/453/pil.

## Kini aarun ìta?

Kokoro aarun aranmọ alailefojuri ni o nfa ìta.
O fẹrẹ jẹ wipe gbogbo eniyan to nii yoo ni iba lile, ara sisu yoo si fa ailera ara. Awọn idiju aarun ìta pẹ̀lú awọn àrànmọ́ àyà, giri, encephalitis (aarun ọpọlọ), ati ọpọlọ bibajẹ. Ninu awọn iṣẹlẹ lile, aarun ìta le pa eniyan.

## Kini ibà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan?

Kokoro ailefojuri kan lo ma nfa bà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan eyiti o le yọri si iba, ori fifọ, ati inira, isun wiwu ni oju, ọrun ati agbọ̀n. O le yọri si iditi patapata, kọọli titanka ati encephalitis (ọpọlọ wiwu).

## Kini ìta pípọ́n?

Ìta pípọ́n (Ìta Gamani) jẹ́ aarun ti kokoro ailefojuri kan nfa. Kii saba le laarin awọn ọmọde o si le lọ lai s'akiyesi rẹ, sugbọn ita pipọn ninu oyun le gidigidi fun awọn ọmọ ikoko ti a ko tii bi. O le ba iriran, igbọran, ọkan ati ọpọlọ wọn jẹ gidigidi. Ipo yi ni a npe ni ààmì ìta pípọ́n líle (CRS).

## Kini abẹrẹ ajẹsara MMR?

O ni awọn ẹda kokoro ailefojuri ti ko lagbara ti ààyè ìta , ibà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan ati ìta pípọ́n. Nitoripe awọn kokoro ailefojuri naa ko lagbara, awọn eniyan to ti gba abẹrẹ ajẹsara naa ko le ko ran awọn eniyan yooku. Ni UK a ni awọn abẹrẹ ajẹsara MMR meji. Awọn mejeeji nsiṣẹ daradara; ọkan ni porcine gelatine ekeji kosi ni. Bi o ba fẹ ki ọmọ rẹ gba abẹrẹ ajẹsara porcine gelatine l'ọfẹ, ba osiṣẹ nọọsi tabi GP sọ.

## Bawo ati nigbawo ni abẹrẹ ajẹsara naa ṣe le jẹ gbigba?

Awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára naa yoo jẹ gbigba sinu isan itan tabi oke apa. A ma n funni ni ọmọ ọdun kan lẹyin ti ajẹsara ti ọmọ gba lọdọ iya wọn ba yọ danu. O gbọdọ tun gba abẹrẹ keji ti abẹrẹ ajẹsara saaju ki ọmọ rẹ to bẹrẹ ile-iwe ni bii ọdun 3 ati osu 4 ni ọjọ-ori.



## Bawo ni abẹrẹ ajẹsara MMR ṣe munadoko si?

Abẹrẹ ajẹsara MMR ni o ti wa fun gbígbọn awọn ààrùn mẹtẹẹta yii ninu awọn ọmọde wẹrẹ gẹgẹbi wọn ti s'afihan rẹ ni UK ni ọdun 1988.

## Ǹjẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára MMR yóò ní àwọn ìdijú kankan?

Awọn orisii kokoro ailefojuri mẹta ninu abẹrẹ ajẹsara ma n siṣẹ ni akoko ọtọtọ o si le fa awọn idiju lẹyin abẹrẹ akọkọ:

- Ọjọ 6 si 10 lẹyin gbigba abẹrẹ ajẹsara, bi apa ìta abẹrẹ ajẹsara naa ti bẹrẹ lati siṣẹ, bi ọkan ninu ọmọ 10 le ni iba awọn kan si le ni ara sisu to dabi ìta, ati wipe ounjẹ le run si wọn
- bii ọkan ninu gbogbo awọn ọmọ 1000 to ti gba abẹrẹ ajẹsara le ni giri ti iba nfa. Eyi ni a npe ni 'giri iba'. Ẹwẹ, awọn ọmọ ti wọn ko tii gba abẹrẹ ajẹsara ti wọn si ni ìta, le ni ilọpo mẹta seeṣe ki wọn ni giri
- bii ọsẹ mẹta lẹyin abẹrẹ ajẹsara MMR, gẹgẹbi apa ibà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan ṣe bẹrẹ iṣẹ, awọn ọmọ kan si le ni awọn aami to jọ ti ibà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan (iba ati awọn isun wiwu)

**MMR jẹ ọna to ni aabo julọ lati dabobo ọmọ rẹ** tako ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan ati ìta pipọn.

- ko wọpọ, awọn ọmọ le ni oju ara to jọ mọ ara bibo ni ọsẹ 6 lẹyin gbigba abẹrẹ ajẹsara. Eyi ma nsaba waye latari ìta tabi ìta pupa inu abẹrẹ ajẹsara naa. Bi o ba rii awọn ọju ara bi eyi, gbe ọmọ rẹ lọ si ọdọ dokita lati ṣe ayẹwo. Dokita rẹ yoo sọ fun ọ bi o ṣe le mojuto ara sisu ati bi o ṣe le dabobo ọmọ rẹ ni ọjọ iwaju
- keere si ọkan ninu ọkẹ aimọye ọmọ le ni encephalitis (ọpọlọ wiwu) lẹyin abẹrẹ ajẹsara MMR. Ẹwẹ, bi ọmọ kan ba ni aarun ìta, aaye didagba encephalitis wa laarin ọkan ninu 200 ati ninu 5,000

## Bi ọmọ mi ba ni aibaramu si ẹyin?

Abẹrẹ ajẹsara MMR ni a le rọra fun awọn ọmọ ti wọn ti ni aibaramu lile (atunbọtan anaphylactic) si ẹyin. Bi o ba ni ifoya kankan, ba olubẹwo ilera, nọọsi tabi dokita rẹ sọrọ.

## Njẹ abẹrẹ ajẹsara MMR ni gelatini?

Ni UK, a ni awọn abẹrẹ ajẹsara MMR meji to nsiṣẹ daradara. Ọkan ninu wọn ní gẹlatini ti ikeji kosi ni. Bi o ba niifẹsi lati gba abẹrẹ ajẹsara naa ti ko ni porcine gelatini, ba osiṣẹ nọọsi tabi GP. O le wo Ìwé-pélébé Ìwífún Aláìsàn ti MMR:

**Priorix:**
www.medicines.org.uk/emc/product/1159/pil

**MMRVAXPRO:**
www.medicines.org.uk/emc/product/6307/pil

# Ma s’akiyesi aarun kọ̣ọli ati septicaemia

Awọn aarun kọ̣ọli ati septicaemia le pipọ. O ṣe pataki pe ki o mọ awọn ààmi ati ami aarun ki o si mọ ohun to yẹ ki o ṣe ti o ba ri wọn.

Awọn aami kọ̣ọli ati septcaemia le jọ ti otutu tabi ọfinkin (iba, eebi, inira ati aifarabalẹ).

Ẹwẹ, ẹnikọọkan pẹlu aarun kọ̣ọli tabi septicaemia le ṣe aisan gidigidi laarin wakati, o wa ṣe pataki lato mọ awọn aami ati aami aarunawọn ipo wọnyi.



## Kíni kọ́ọ́lí?

Kọọli jẹ ikọlu itẹnu ọpọlọ. Kọọli le waye nipa ọpọlọpọ kokoro arun tabi kokoro ailefojuri.

Ikọlu pẹlu kokoro aarun meningococcal le fa kọọli, septicamia (majele ẹjẹ), pericarditis (itẹnu apo ọkan wiwu) ati àgì (orikerike ara wiwu).

Ninu awọn ọmọ ìkókó, awọn koko aami aarun kọọli le pẹlu:

- igbe ẹkun gooro
- inira bi wọn ba gbe
- awọ-ori fifẹ
- òògbé ati aidaraya - to jẹ inira lati ji
- didaralẹ ati ailokun
- gigan ati gbigbọn  (giri)
- kikọ ounjẹ, bíbì
- awọ ara toti funfun, to tin yipada si bulu.
- iba



## Kini septicaemia?

Septicaemia jẹ ipo lile nigbati isun ẹjẹ ba ti ni ikọlu. Awọn aami ọwọ ati ẹsẹ tutu, awọ ara funfun, bibi and oorun asunju tabi inira lati ji le wa ni kiakia. Bi o ba fura si septicaemia, wa iranlọwọ ni kiakia.

Ninu awọn ọmọ ìkókó, awọn koko aami aarun septcaemia ni:

- mimi lemọlemọ tabi lọna to sọwọn
- awọ ara toti funfun, to tin yipada si bulu.
- iba pẹlu otutu ọwọ ati ẹsẹ
- gbigbọn
- bibi ati kikọ ounjẹ
- oju ara pupa tabi elese aluko ti o le parẹ labẹ idamu (ṣe ayẹwo gilasi ti a s'alaye ni oju ewe to ka)*
- inira lati isan riro tabi ẹsẹ riro tabi orikerike ara riro
- didaralẹ
- airi oorun sun

O ṣe pataki lati ranti wipe kiiṣe gbogbo eniyan ni yoo ni gbogbo awọn aami aarun ti a to silẹ, ati wipe atokalẹ awọn aami aarun yii ko lopin. Bi ẹnikẹni ba ni awọn aami aarun kan, paapaa julọ oju ara pupa tabi elese aluko, wa iranlọwọ iṣegun ni kiakia. If yu nor fit get kansi dokita rẹ, tabi ti o tun ni ifoya nipa gbigba imọran, gbẹkẹle ọkan rẹ ki o si mu ọmọ rẹ lo si ẹka pajawiri ile iwosan to wa ni itosi rẹ.

*Lori awọ to dudu, yẹ inu ipenpeju tabi oke ẹnu wo nibiti oju rẹ ti le han kedere sii

## ‘Ayẹwo gilasi’



Tẹ ẹgbẹ gilasi imumi mọ tako ara sisu ki o si wo boya ara sisu naa to parẹ ti o si padanu awọ labẹ idamu. Bi awọ naa ko ba yatọ, kansi dokita rẹ ni kiakia.

## Níbo ni mo ti le gba ìwífún síwájú síi?

Awọn alanu wọnyi pese iwifun , imọran ati iranlọwọ:

**Meningitis Research Foundation**
Nọmba ipe ọfẹ 080 8800 3344
(Agogo 9 owurọ si 10 alẹ ni opin ọsẹ,
Agogo 10 owurọ si 8 alẹ ni opin ọsẹ ati isinmi)
www.meningitis.org

**Meningitis Now**
iranlọwọ ipe wakati 24 - 0808 8010 388
www.meningitisnow.org

O tun le bi dokita, osiṣẹ nọọsi tabi alejo ilera rẹ fun imọran, tabi ki o pe **NHS** lori **111**.

### Awọn obi ati olutọju le jábọ̀ àwọn ìdíjú abẹ́rẹ́ àjẹsára àti òògun tí o furasí nípasẹ̀ Ètò Yellow Card.

Eyi le jẹ siṣe lori ayelujara nipa sisabẹwo si **yellowcard.mhra.gov.uk** tabi nipa pipe nọmba Yellow Card lori **0800 731 6789**. O le lo kodu QR tabi nipa gbigba apuu Yellow Card sori fonu.

SCAN ME

# Ilakalẹ eto gbigba abẹrẹ ajẹsara ọmọde lati Osu Kẹsan, ọdun 2024

| Ọjọ-ori tó yẹ | Awọn aarun to tako | Abẹrẹ ajẹsara ti o gba |
|---|---|---|
| Ọmọ ọsẹ mẹjọ | Diphtheria, tetanus, pertussis (ikọ lile), rọparọsẹ, *Haemophilus influenzae* type b (Hib) ati jẹdọjẹdọ B | DTaP/IPV/Hib/HepB |
| | Meningococcal ipin B (MenB) | MenB |
| | Rotavirus gastroenteritis | Rotavirus[2] |
| Ọmọ ọsẹ mejila | Diphtheria, tetanus, pertussis, rọparọsẹ, Hib ati jẹdọjẹdọ B | DTaP/IPV/Hib/HepB |
| | Pneumococcal (13 serotypes) | Pneumococcal conjugate vaccine (PCV) |
| | Rotavirus | Rotavirus[2] |
| Ọmọ ọsẹ mẹrindinlogun | Diphtheria, tetanus, pertussis, rọparọsẹ, Hib ati jẹdọjẹdọ B | DTaP/IPV/Hib/HepB |
| | MenB | MenB |
| Ọmọ ọdun kan (l'ọjọ tabi lẹyin ọjọ ibi akọkọ ọmọ naa) | Hib and MenC | Hib/MenC |
| | Pneumococcal | Àlékún abẹrẹ ajẹsara PCV |
| | Ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan ati ìta pipọn (ìta Gamani) | MMR |
| | MenB | Àlékún abẹrẹ ajẹsara MenB |
| Ipin ọjọ-ori itọju ọmọde to yẹs[4] | Ọfinkin (ọdọọdun lati osu kẹsan) | Abẹrẹ ajẹsara ààyè ti npa ọfinkin LAIV[3,6] |
| Ọmọ ọdun mẹta ati osu mẹrin tabi laipẹ | Diphtheria, tetanus, pertussis ati rọparọsẹ | dTaP/IPV |
| | Ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wíwú tí o le gan ati ìta pipọn. | MMR (yẹ abẹrẹ akọkọ to gba wo) |
| Ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin to ti pe ọdun mejila si mẹtala | Aarun jẹjẹrẹ ati oju ara wiwu ti pato iru human papillomavirus (HPV) nfa | HPV[5] |
| Ọmọ ọdun mẹrinla (ọdun ile-iwe 9) | Tetanus, diphtheria ati rọparọsẹ | Td/IPV (Ṣe ayẹwo ipo MMR) |
| | Ipin meningococcal A, C, W ati Y | MenACWY |

**[1]** Gún abẹrẹ inu isan sinu isan deltoid l'oke apa tabi inu ati ita itan. **[2]** Abẹrẹ ajẹsara Rotavirus gbọdọ jẹ gbigba lẹyin yiyẹ esi ayẹwo SCID wo. **[3]** O ni porcine gelatine ninu. **[4]** Wo lẹta ọfinkin ọdọọdun ni: www.gov.uk/government/collections/annual-flu-programme. **[5]** Wo Green Book HPV Ori 18a fun awọn alaye lori fifun awọn ọdọ ti o padanu ajẹsara ti yoo nilo abẹrẹ mẹta ni abẹrẹ ajẹsara. **[6]** Bi LAIV (abẹrẹ ajẹsara ààyè ti npa ọfinkin) ko ba ṣee lo tabi jẹ abẹrẹ ajẹsara ọfinkin ti ko sisẹ ti kosi peye (yẹ Akori 19 Iwe Alawọ Ewe wo fun alaye). **[7]** Wo Green Book HPV Ori 28a fun awọn alaye lori awọn ẹgbẹ to yẹ pẹlu olukuluku to ni ajẹsara rirẹwẹsi lati ọjọ-ori 50.

# Alekun abẹrẹ ajẹsara fun ẹnikọọkan pẹlu awọn ipo iṣegun to duro le

| Ipo Işegun | Awọn aarun to tako | Awọn abẹrẹ ajẹsara ti o nilo[1] |
|---|---|---|
| Kosi ọlọ mọ abi ọlọ to dasẹ silẹ (eyiti o pẹlu ààrùn runmọlegun ati ààrùn ikun) | Ipin meningococcal A, C, W ati Y<br>Pneumococcal<br>Ọfinkin | MenACWY<br>MenB<br>PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun |
| Awọn afisinu eti | Pneumococcal | PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori) |
| Awọn ipo èémí ati ọkan (bii ikọ ife lile, aarun ẹdọforo lile, ati ọkan to da iṣẹ silẹ) | Pneumococcal<br>Ọfinkin | PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun |
| Awọn ipo isan to buru gan (bii aisan ara gbigbon tabi aarun isan, tabi ailagbara ikẹẹkọ) | Pneumococcal<br>Ọfinkin | PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun |
| Itọ suga | Pneumococcal<br>Ọfinkin | PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun |
| Aarun kidirin to buru gan (CKD) (pẹlu itọju haemodialysis) | Pneumococcal (ipele 4 ati 5 CKD)<br>Ọfinkin (ipele 3, 4 ati 5 CKD)<br>Jẹdọjẹdọ B (ipele 4 ati 5 CKD) | PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun<br>Jẹdọjẹdọ B |
| Awọn ipo ẹdọ to | Pneumococcal<br>Ọfinkin<br>Jẹdọjẹdọ A<br>Jẹdọjẹdọ B | PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun<br>Jẹdọjẹdọ A<br>Jẹdọjẹdọ B |
| Haemophilia | Jẹdọjẹdọ A<br>Jẹdọjẹdọ B | Jẹdọjẹdọ A<br>Jẹdọjẹdọ B |
| un tabi itọju[4] | Pneumococcal<br>Abẹrẹ ajẹsara Shingles<br>Ọfinkin | PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2,3]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Shingrix – ju ọjọ-ori 50 lọ[5]<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun |
| Aiṣedede iṣẹ ẹya ara (eyiti o pẹlu gbogbo awọn to ngba itọju ti ngbogunti aiṣedede iṣẹ eya ara) | Ipin meningococcal A, C, W ati Y<br>Pneumococcal<br>Ọfinkin | MenACWY<br>MenB<br>PCV13 (Toto ọdun mẹwa l'ọjọ-ori)[2]<br>PPV23 (lati ọdun meji l'ọjọ ori)<br>Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ọdọọdun |

**[1]** Yẹ akori to bojumu ti Iwe Alawọ Ewe wo fun agbekalẹ eto ni pato: www.gov.uk/government/collections/immunisation-against-infectious-disease-the-green-book. **[2]** Bi o ba ti pe ọmọ ọdun meji si mẹwa ti kosi tii gba abẹrẹ ajẹsara tabi o ti gba aabọ abẹrẹ ajẹsara tako ikọlu pneumococcal, abẹrẹ PCV13 kan. **[3]** Fun eyikeyi ọjọ-ori to wa ninu ajẹsara rirẹwẹsi. **[4]** Ro eto abẹrẹ ajẹsara ọfinkin ọlọdọọdun fun awọn ara ile ati fun awọn ti wọn nṣẹ itọju fun awọn eniyan pẹlu awọn ipo yii. **[5]** Yẹ Green Book Shingles Ori 28a wo www.gov.uk/government/publications/shingles-herpes-zoster-the-green-book-chapter-28a.

# Àsàyàn Ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára èwe

| Ipin Afojusun | Ọjọ-ori ati agbekalẹ eto | Ààrun | Abẹrẹ Ajẹsara to nilo |
|---|---|---|---|
| Awọn ọmọ ti awọn Iya wọn ni jẹdọjẹdọ B | Lasiko ibi, o ti dagba to ọsẹ mẹrin ati osu 12[1,2] | Jẹdọjẹdọ B | Jẹdọjẹdọ B (Engerix B/ HBvaxPRO) |
| Awọn ìkókó ni agbegbe orilẹ-ede pẹlu isẹlẹ TB >= 40/100,000 | Bii ọjọ ori 28[4] | Ikọ awuju | BCG |
| Awọn ìkókó pẹlu obi kan tabi obi agba ti a bi si orilẹ-ede ti iṣẹlẹ ti ga[3] | Bii ọjọ ori 28[4] | Ikọ awuju | BCG |
| Awọn ọmọ ni ẹgbẹ ewu ilera | Lati ọmọ osu mẹfa si ọmọ ọdun 17 | Ọfinkin | LAIV tabi abẹrẹ ajẹsara ọfinkin ti ko sisẹ ti a ti kọ silẹ si LAIV tabi ọjọ-ori ti ko tii pe ọdun meji |
| Awọn Obinrin oloyun | Ni eyikeyi ipele oyun lakoko ofinkin | Ọfinkin | Abẹrẹ ajẹsara ọfunkin ti ko sisẹ |
| | Lati ọsẹ 16 oyun[5] | Ikọ awukanlẹ | Tdap or dTaP/IPV |
| | Lati oyun ọsẹ 28 | RSV | Abẹrẹ ajẹsara RSV |

**[1]** Gba ẹjẹ fun HBsAg ni osu 12 lati yago fun iranmọ. **[2]** Ni afikun abẹrẹ ajẹsara hexavalent (Infanrix hexa tabi Vaxelis) ni a funni ni ọsẹ 8, 12 ati 16. **[3]** Nibiti isẹlẹ TB ọdọọdun wa >= 40/100,000 – see www.gov.uk/government/publications/tuberculosis-tb-by-country-rates-per-100000-people. **[4]** Yẹ abajade isayẹwo SCID wo saaju ki o to funni ni BCG. **[5]** O yẹ ko saaju ọsẹ iloyun 32 sugbọn a si tun le fun-un lẹyin ẹsẹ 32.

Produced by
**UK Health Security Agency**

© Crown copyright 2024
2024QG1YO Yoruba 1p 500K AUG 2024
UK Health Security Agency gateway number: 2024525

Abajade akọkọ yii ni a tẹ jade ni Osu Kejila, Odun 2019.

Bi o ba nilo ẹda awọn iwe pelebe yii, jọwọ ṣe abẹwo si, www.healthpublications.gov.uk lati kansi Ila-itaja Itẹwe Ilera. Ph1: 0300 123 1002.
Minicom: 0300 123 1003 (Agogo 8 owurọ si 6 irọlẹ, Ọjọ aje si Ẹti).

Jọwọ lo koodu ọja: 2024QG1YO Yoruba

**www.nhs.uk/vaccinations**